
# ọ̀fìnkìn:
# àwọn èrèdí 5

## láti gba abẹ́rẹ́ àjẹsára náà



1. **Dáàbòbò ara rẹ**
   Abẹ́rẹ́ àjẹsára náà yóò dáàbòbò ọ́ tako ọ̀fìnkìn àti àwọn ìdíjú bíi àìsàn gbọ̀fungbọ̀fun àti òtútù àyà
2. **Dáàbòbò ìdílé àti àwọn ọ̀rẹ́ rẹ**
   Gbígba abẹ́rẹ́ àjẹsára náà yóò dáàbòbò ọ̀pọ̀ àwọn ọ̀rẹ́ àti ìdílé tó wà nínú ewu
3. **Kò nílò abẹ́rẹ́ kankan**
   Abẹ́rẹ́ àjẹsára fínfín sí imú kò nira ó sì rọrùn láti gbà
4. **Ó dára ju níní ọ̀fìnkìn lọ**
   Abẹ́rẹ́ àjẹsára fínfín sí imú ńdáàbòbò ọ́ tako ọ̀fìnkìn, a ti fún ọ̀kẹ́ àìmọye ènìyàn l'ágbàáyé ó sì ní àkọsílẹ̀ ààbò tó gbópọn
5. **Yàgò fun pípàdánù àwọn ànfààní**
   Bi o bá ní ọ̀fìnkìn, o le wà ní àilera fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọjọ́ tí o kò sì ní le ṣe àwọn ǹkan tí o gbádùn

Fún ìwífún síwájú síi s'àbẹ̀wò sí
**www.nhs.uk/child-flu**

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ọmọ ti gba abẹ́rẹ́ àjẹsára fínfín sí imú èyítí ó jẹ́ abẹ́rẹ́ àjẹsára tí wọ́n yàn láàyò. Abẹ́rẹ́ àjẹsára oní gígùn náà wà èyítí kò ní gẹlatini láti ara àwọn ẹlẹ́dẹ̀ (porcine gelatine).

Flu immunisation
Helping to protect you against flu

© Crown copyright 2024. Product code: FLU5RS24YO.
UK Health Security Agency gateway number: 2024318. If you want to order more copies of this poster, please visit: healthpublications.gov.uk or call 0300 123 1002.